**Blackpod**
**Capsid**

*lati k'apa arun Koko wọnyi patapata lo*

**MYSTO SPRAYING EQUIPMENT**
"MYSTO" Model No. 159.
—eyiti o jẹ pe egbogi olomi fun titẹjade ti o wa ninu rẹ jẹ galọnu mẹta



" UNAMYST "
—ti o jẹ egbogi alafi—owọ—yi ti o wa ninu rẹ jẹ galọnu mẹta.
gbogbo ẹka irinṣẹ ti a fi nlo wọn ni tita ni owo pọọku.

*pẹlu awọn ẹrọ irinṣẹ wọnyi lo*

Perenox ati Perepod fun Blackpod ati fun capsid to Didimac 25.

O wa ni gbogbo ẹka ile itaja
**The United Africa Co. of Nigeria Ltd. and U.A.C. (Technical) Ltd.**

# IROHIN KAKIRI ILU

## *Isinku baba Wule larinrin*

IBADAN.

BI baba Wule ti dakẹ ti o si wole ni awọn ọmọ-oloku ti nṣe ile ponti ti nwọn si nṣe odẹde 10'ka. Kọ awọn ẹnia pataki pataki ti o pe si'bi isinku na: awọn Ọgbẹni bi Hamzat, Tiamiyu Are, Ladipo Agbo-ola, Rafiu Ibrafu, Akangbe ati Sikiru Ajadi.

Ki Oluwa pa aṣẹ oku na re, ki O si fi ọmọ ire gbẹ-hin awọn ọmọ-oloku ati gbogbo awọn alabaṣepe ọjọ na.

## Irohin Alagbagba

Lati ọwọ T. A. Odubanmi
(Aṣoju Iwe Irohin Yoruba)

ALAGBAGBE

OJỌ ko ni gbagbe ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejila oṣu kẹfa ọdun yi jẹ ni agbegbe yi fun gbogbo olufẹ ilọsi-waju. Nitoripe ni ọjọ na ni ile-iwe ọfẹ fun awọn agba-lagba alakobere, eyiti awọn agbalagba okunrin merin-dinlogbon ati obinrin mefe pejọ lati kọ bi a ti nka iwe ati bi a ti nkọ ọ.

Ki agogo mẹrin ti awọn Igbimo ẹkọ Agba fi ipade yisi ile-iwe na si to lu ni ẹsẹ gbogbo awọn akẹkọ lọkun-rin ati lobinrin ti pe. Ni-pati a si di agogo merin gere ni awọn ẹnia patakipataki bi Alaga Igbimo ẹkọ Agba ti bere si ba awọn akẹkọ sọro lṣiri.

Ẹkọ kiko si bere ni dede agogo merin abo. Iyanu na ko si mọ ni kekere lati ri okan ninu awọn akẹkọ wọnyi, eniti o to ẹni ọgọta ọdun, nigbati o ko "Baba ba a" sinu iwe rẹ ti o si nka a fun oluko rẹ. A dupẹ lọwọ Olorun fun ibukun rẹ lori wa ni agbegbe yi nipa ti ẹkọ agba yi o.

A ki awọn Igbimo Ẹkọ Agba ati awọn oluko Ile-iwe C. A. C. School, ti Ala-gbagba ti o mu ki anfani yi kan wa nihin. Ki Oluwa ki o tubọ ma a ran nyin lọwọ o.

## *Oloye Ṣoyọmbọ di Oluwo Erunbe*

ERUNBE, ABẸOKUTA.

EṢE awọn ẹnia pataki pataki ni o pe si ile Oloye Ṣoyọmbọ, Niado Erunbe nigbati nwọn nfi Oloye na jẹ Oloye Oluwo Erunbe, ninu oṣu t'okoja yi. Oloye Faloye, Apena Erunbe ni o ju Ewe Oye (Ewe Akoko) le e lori.

Oluwo na ti jijẹ ati mi-mu te gbogbo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na lọrun ti ti ile ọjọ na fi su. Eyẹ ọjọ na buaiya o le gongo. Irohin ko to amojuba ni.

Oye a m'ori o.

## *Ikomọ ọmọ Ọtẹshile dun*

IBADAN.

LENULOLOYI ni Ọgbẹni Oluyinka Ọtẹshile ku omokonrin ti Ọlorun fi ta on ati aya rẹ lọrẹ jade, nwọn si sọ ọmọ na ni Olufemi Ayọdele Ọtẹshile. Baba ọmọ na fi oriṣiriṣi onjẹ ati ọti tẹ gbogbo awọn alabaṣeye ọjọ na lọrun.

Ninu awọn ẹnia pataki pataki ti o pe si'bi aṣeye ọjọ na ni awọn Ọgbẹni B. A. Ọtẹshile, L. A. K. Ogun-wolu, Oloye Sọgaolu, Ọgbẹni J. Oṣosope Johnson ati Iyaafin Abẹbi Sonyaolu.

Ire a kari o.

## Ajobiewe ṣe igbeyawo

ỌKA LẸBA ỌWỌ.

IROHIN ko to amojuba ni igbeyawo ti Ọgbẹni Elijah Ajobiewe ṣe lenulo-loyi. Gbogbo ẹsẹ gbajumo ni o pe si'bi igbeyawo na. Ọkọ-iyawo si fi onjẹ ati ọti tẹ wọn lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu wọn ni awọn Ọgbẹni J. O. Sloh, K. A. Ọtun, B. O. Ojuse, O. A. Ajobiewe, Sanni Epe ati James Agboola.




## Western Region Production Development Board

The Board invites applications for a few vacancies in the following grades:—

(a) AGRICULTURAL UNIT MANAGERS.
£960 x 42—£1,070; £1,100 x 55—£1,320
(plus expatriation pay, where applicable, as follows):—

£690 — £968 (basic) — £180.
£993 — £1,070 " — £240
£1,100 — £1,320 " — £270

(b) AGRICULTURAL ASSISTANT UNIT MANAGERS.
£600 x 30 — £750.

(c) AGRICULTURAL SENIOR FIELD ASSISTANTS.
£468 x 24 — £564.

(d) (i) FIELD ASSISTANTS GRADE I.
£291 x 15 — £336; £354 x 18 — £426.
(ii) FIELD ASSISTANT GRADE II.
£153; £159 x 12 — £201.

In every case point of entry into scales will depend on qualification and experience.

QUALIFICATIONS FOR (a)

A degree or diploma in agriculture plus several years field experience including labour control. Specialised knowledge of cocoa and oil palm would be an advantage. Successful applicants will be required to take charge of large plantations and must be competent in all aspects of plantation management.

QUALIFICATIONS FOR (b)

A diploma in agriculture from any recognised local or overseas institutions, familiarity with all aspects of plantation management, or sound technical training in agriculture backed by several years of wide experience in all aspects of plantation management.

QUALIFICATIONS FOR (c)

Senior Cambridge School Leaving Certificate or its equivalent and in addition a diploma from the local Schools of Agriculture and several years of field experience, including control of labour, keeping of farm records and writing reports.

QUALIFICATIONS FOR (d)

Senior Cambridge School Leaving Certificate or its equivalent plus technical training in a recognised local Agricultural School. In the case of (d) (i) some years of field experience is essential.

Applications in applicant's own handwriting should be forwarded to

THE PERSONNEL SECRETARY,
W. R. P. D. Board,
Secretariat,
Ibadan.

to reach him not later than 30th April, 1956.

Only applications of those selected for interview will be acknowledged.

## IGBEYAWO AJAGBE minringindin

INISHA-OSHOGBO.

ESE awon gbajumo pe s'ibi igbeyawo Sunmonu Ajagbe ati Sabi Abeo ti nwon se lenuloloyi. Oko iyawo, baba-oko iyawo awon Ogbeni Jimadu ati Aliyu na'wo na'ra lojo na. Ajeti ati amuti ni awon alabaseye ojo na fi jije ati mimu se.

Oloja R. A. Idowu, awon Ogbeni Amodu Salako, G. P. Bandele, Amos Ladipo, Jimo Akanji ati Salami Abiku-so-Ologun-d'eke ba won se eye ojo na de opin.

## Adajo da Yesufu Odulana lare

ABEOKUTA.

NI ojo kokanlelogun osu kejila odun ti o koja yi (21.12.55) ni Adajo Agba Kotu Ake, Ogbeni Ilori da Yesufu Odusina lare lori ejo ile oja Obafemi ti on pelu Suberu Sokunbi nse ejo le lori.

Nigbati Adajo gbo t'enu t'otun ati t'osi, ti o si gbo oro enu awon elerí, o si ri ododo oro dimu pe nitoto ni Suberu Sokunbi ti ta ile na fun Yesufu Odusina, ni Adajo na ba dajo pe Suberu Sokunbi jebi, ti o si kilo fun un pe ko tun gbodo de ibi ile na mo lai.

## AKIYESI PATAKI

Nipa aise deede oko oju omi ti nko iwe "Irohin Yoruba" lati ilu Naijiria lo si Oke Okun (Gold Coast) awon alase iwe irohin na ti se eto fun anfani gbogbo awon ti nka iwe na ni Oke Okun.

Nipa eto titun yi, Iwe IROHIN YORUBA yio ma a de Oke Okun ni ojo Alaruba ni osese, yio si ma a de Kumasi ni osan ijo Alamisi ti nse ojo keji.

A se ikede yi fun gbogbo awon ti nka Iwe Irohin yi ti nwon si ngbe ilu Ankara (Accra) ti nwon si ngba ju iwe kan lo ki nwon ma a lo gba iwe won ni ile ise *TARZAN* ti mbe ni Accra; awon to si ngbe Kumasi ki nwon ma a lo gba ti won ni ile ise *TARZAN*, ni Kumasi.

Fun anfani gbogbo awon ti nfe lati ma a ka iwe yi, ti ko si ti i mo ibi-ti yio ti ma a gba a, a ti si eka ile ise "DAILY SERVICE" ati Iwe "Irohin Yoruba" si Accra, HANSEN ROAD, ACCRA tabi P. O. Box, 1458, Accra, Gold COAST.


FUN AGBARA

NIBI ISE ATI ERE





Hommel's Haematogen —olomi EJE-AKO-MALU ti o dara —le fun iwo paapa na pelu ni gbogbo nkan ti nfun ara l'agbara bi irin ti o nso ni di Ogagun Ere-ije— "Olympic".



FUN AGBARA NIBI ISE L'OSAN

FUN ALAFIA NINU ISIMI ATI ERE

MU ...HOMMEL'S

HÆMATOGEN

Nwon nta o sinu igo keekeke (8 fluid oz.) ta kakiri gbogbo ile itaja-egbogi, ati lodo awon asoju wa ni Naijiria

ALMAN PHARMACY LTD., 1 Victoria St., P. O. Box 461, Lagos, Nigeria.


## Njemanze ati Iyawo re pelu awon merin ti Kotu-Nla ti Apapo Ijoba Naijiria da lebi iku pipa ti nwon pa Njemanze na



MICHAEL ADEYEMO



Israel Njemanze



SAMUEL JEGEDE



CYRIL ANIKWE



Iyaafin Njemanze



PETER NWANGU


Fi apa-iye si moto re!




Mobiloil tuntun pataki yi njeki ero re sise iyna iyanu—ni gbogbo orisirisi ona—o dabi igbati o ba fi apa iye si moto ayokele re ni! Epo moto alailegbe yi le sise bakanna nigba erun tabi nigba otutu. Ki i jeki ero yonu tabi ki o kidanpapa rara—A ma mu ki emi ero o gun ni ilopo meji. Mobiloil tuntun pataki yi ki i jeki ero tete baje, a ma a mu ki gbogbo irinse inu ero ma a sise daradara— fun eyi, ki i si mu ki ero je epo, a ma a mu ki ero ma a sure ijje pelu igbadun, a ma a mu ki ero je epo die fun opolopo meli. Lo Mobiloil tuntun pataki yi wo fun iyato ti wa a ri ni ese-ayika-keke!

NEW Mobiloil SPECIAL

O dara fun awon ogbologbo moto -- oranyan si ni fun awon moto titun!

Mobil Oil Nigeria Limited

E maa polowo oja nyin sinu iwe
IROHIN YORUBA
ki e si tun maa ka iwe na fun
irohin aladun nigbagbogbo.

AWON OGBOLOGBO
(SCRAP)
OJE (LEAD)
IDE (BRASS)
BABA (COPPER)
AWON ALOKU IRIN
ERO MOTO (RADIATORS)
PAANU AYO (ALLUMINIUM)
JE OWO
Ko won wa ta fun
BUCK (NIGERIA) LTD.,
2, AERODROME ROAD, APAPA.
TELEPHONE
55177.




'DARAPRIM'



Eyọ koro kan l'ọsẹ kan m'ara wọn le!

Dabobo awọn ẹbi rẹ lọwọ Akọ-iba atipe ki o ran awọn ọmọ rẹ lọwọ lati dagba dada ki nwọn si le lagbara. Awọn agbalagba nlo koro kan 'Daraprim' kan l'ọsẹ kan. ọmọ ti o ba dagba koja ọdun marun, idaji koro, ti ko ba dagba to ọdun marun, idamerin koro. 'Daraprim' ko ladun lenu ko si nyi enia lawọ ara pada.

O gba'nia laju, o daju ju, owo rẹ si dinku.

THE MARK OF BURROUGHS WELLCOME & CO.
Agents for British West Africa: J. L. MORISON, SON & JONES (NIGERIA) LTD., LAGOS
J. L. MORISON, SON & JONES (GOLD COAST) LTD., ACCRA

Printed by the Amalgamated Press of Nigeria Limited, 5/7 Apongbon Street, Lagos. Editor: S. M. Ademuyiwa. 9 Chapel Street, Lagos.

# IJỌBA YIO KỌLE F'OṢIṢẸ

*Lati oju ewe kini*

a se eto yi. Awọn memba igbimọ na yio jẹ mẹjọ laika alaga kan ti nwọn yio ni l'arin wọn mọ wọn. Merin ninu awọn memba na ni yio je asoju awọn oṣiṣẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun.

Igbimọ na yio fun awọn oṣiṣẹ ni owo-agbasilẹ lati fi ko awọn ile si Ipinlẹ Iwọ-Orun tabi Eko eyi ti awọn oṣiṣẹ na tabi awọn ẹbi wọn yio ma a gbe. Oṣiṣẹ na si le ko'we ẹbẹ fun owo-agbasilẹ lati fi ra ilẹ ti yio kọle le lori tabi lati fi ra ile.

Ki o to ni etọ fun owo-agbasilẹ yi o ni lati jẹ pe:

(1) ile ti o ngbe gan an wa ni Ipinlẹ Iwọ-Orun tabi ni Eko;

(2) Ese rẹ ti rande lenu iṣẹ Apapo Ijọba Naijiria tabi ti Ipinlẹ Ijọba tabi ti Ijọba Ibilẹ ilu tabi iṣẹ Minisipa (ti o ba jẹ pe awọn ti nwọn fi Eko se ibugbe ni, nwọn ni lati jẹ oṣiṣẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun tabi ti Ijọba Ibilẹ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun).

(3) Iye owo-iṣẹ rẹ ko si gbọdọ din ni ponun mẹdogun l'oṣoosu;

(4) yio wa l'enu iṣẹ ti o ni owo-ifẹhinti ninu (pension) tabi ida'wo pamọ (Provident Fund);

(5) o ni lati ri daju pe ile ti o fẹ lati kọ'le na si gbooro to lati kọle gbigbe le lori;

(6) ki o si ri daju pe ẹtọ rẹ lori ilẹ na ko ni iṣiyemeji ninu.

Owo-agbasilẹ na ko ni le ni ẹgbaaji ponun (£4,000) tabi si owo oṣu mejidinlaadọta ti ẹni ti o ba fẹ lati gba owo-agbasilẹ na ba ngba nibi iṣẹ rẹ, o si ni lati san owo-agbasilẹ na pada tan larin ọjilerugba oṣu (240 months) ti iṣe ogun ọdun, ṣugbọn adasan owo na ko le ju idamerin owo ti oluware ba ngba losu lọ, tabi idamẹrin owo-ifẹhinti lẹnu iṣẹ (pension) ti o ngba ni yio ma a san l'oṣoosu lati le da owo-agbasilẹ fun ile kikọ na pada. Ẹni ti o ba nfẹ lati gba owo-agbasilẹ yi ni lati san an pada tan ki o to dagba to ẹni ọdun marundinlaadọrin (65 years of age.)

## Awolọwọ nilu Jamanu

*Lati oju ewe kini*

Lati igbana ni nwọn si ti bẹrẹ si se ibewo ile iṣẹ ero fun orisirisi iṣẹ ti nwọn si nṣe alaye irin ajo wọn fun idagbasoke ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ati iru iranlọwọ ti awọn le ri gba lati ọdọ awọn ara ilu na, awọn ara ilu na si nṣe ileri iranlọwọ fun wọn gẹgẹbi awọn ilu yoku ti nṣe fun wọn bọ lati ẹhin wa.

## Awọn onija igboro Kano ti gba idajọ

*Lati oju ewe kini*

o wa ni ariwa ẹnu-odi ilu yi, nwọn si doju ija ko awọn Ọlọpa. Nwọn sọ awọn mẹta si ẹwọn ọdun kookan nitoripe nwọn sọpanpa to di oju-ona. Okan ninu awọn ọdaran na gba idajọ ẹwọn odun kan pere fun ẹrọ lọpkusọ ti o sọ.

Mẹtadinlogorin ninu wọn ni o gba idajọ ẹwọn oṣu mẹfa-mẹfa nitoripe nwọn sọ awọn Ọlọpa ni okuta nwọn si ba wọn ja; okan fi ara se ẹwọn oṣu merin nitoripe o di awọn olutọju ẹlẹwọn (warders) lọwọ lẹnu iṣẹ. Mẹta lọ ṣe ẹwọn oṣu mẹta-mẹta fun ija ti nwọn ba awọn Ọlọpa ja. Okọọkan ninu awọn merinla ti nwọn da irukerudo na silẹ lọ ṣe ẹwọn oṣu mẹta-mẹta, awọn ogun enia ni nwọn se ikilọ fun pe nwọn ko gbọdọ ru ofin mọ (bound over).

Awọn ọdọmọdekunrin mẹrinla ni o jẹbi nina ni pasan nitoripe nwọn sọ awọn Ọlọpa l'okuta. Fun iranwọ ti nwọn se lati sọ awọn Ọlọpa l'okuta, ni awọn ọdọmọdebirin onisẹ asewo mẹfa lọ se ẹwọn. omiran ninu wọn fun oṣu kan, ti omiran ju bẹẹ lọ, eyi ti o ti e lọ se ẹwọn ọlọdun kan wa ninu wọn. Bayi ni nwọn pari ẹjọ awọn ọmọ Ẹgbẹ NEPU onijagboro na si o.

Bi egbogi Koko oni - "Four Oaks"
ti ṣe ngmu KOKO DARA ti o si ngmu ki awọn Agbẹ Naijiria JERE PUPỌJU

- Ki i jẹ ki nwọn PADANU nipa pipa gbogbo arun ara igi ati ti eso Koko
- A ma a mu Koko GBILẸ si pupọ l'oko
- A tubọ ma jẹki Koko ni IYE lari
- AGBARA rẹ ni ifọkanbalẹ, atunṣe ati abo



A o ri awọn egbogi koko oni - "FOUR OAKS" yi lọdọ Ẹgbẹ Onisowo Co-operative Supply Association tabi Onisowo Co-operative Produce Marketing Association ni ofisi tabi ni ile itaja wọn. Gbogbo irin ara ẹrọ na ni o wa lọtọọtọ fun tita.

COOP
WESTERN NIGERIA